# “Gbólóhùn meji kan ti wọn fúyẹ́ lori ahọ́n, ti wọn wúwo ninu òṣùwọ̀n, ti Ajọkẹ-aye nífẹ̀ẹ́ si méjèèjì

Lati ọdọ Abu Hurairah, ki Ọlọhun yọnu si i, o gba a wa lati ọdọ Anabi, ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a, o sọ pe: “Gbólóhùn meji kan ti wọn fúyẹ́ lori ahọ́n, ti wọn wúwo ninu òṣùwọ̀n, ti Ajọkẹ-aye nífẹ̀ẹ́ si méjèèjì ni: SUBHAANALLOOHIL AZEEM, SUBHAANALLOOHI WA BIHAMDIHII”.

[O ni alaafia] [Ohun ti wọ́n fi ẹnu kò lé lórí ni]

Anọbi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- sọ nipa gbólóhùn méjì kan ti ọmọniyan maa n pe ni gbogbo iṣesi láìsí inira nibẹ, èsan méjèèjì si tobi ninu òṣùwọ̀n, ati pe Oluwa wa Ajọkẹ-aye ti ọla Rẹ ga si nífẹ̀ẹ́ si méjèèjì: SUBHAANALLOOHIL AZEEM, SUBHAANALLOOHI WA BIHAMDIHII; fun nǹkan ti méjèèjì ko sinu bii iroyin Ọlọhun pẹlu titobi ati pípé, ati fifọ Ọ mọ kuro nibi àléébù.

https://sunnah.global/hadeeth/yo/show/5507

النجاة الخيرية
ALNAJAT CHARITY
لجنة الدعوة الإلكترونية
EDC E-Da'wah Committee